# IṢẸ-IYANU NIPA IWOSAN -- BIBÁ AFẸFẸ ATI OKUN WI

**Johannu 4:46-54; Marku 2:1-12; Matteu 8:1-27**

**ẸKỌ 32 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ṣugbọn a ṣá a li ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa a li ara nitori aiṣedede wa; ìna alafia wa wà lara rẹ̀, ati nipa ìna rẹ̀ li a fi mu wa lara da" (Isaiah 53:5).**

**I Oniṣegun Nla ati Ọkunrin Ọlọla Kan ni Kapernaumu**

1 A bẹ Jesu ki o wo ọmọ ọkunrin ọlọlá Kapernaumu kan sàn, Johannu 4:46, 47; 2:1-11

2 Jesu fi ọ̀rọ wadii igbagbọ́ ati otitọ inu ọkunrin ọlọla yii, Johannu 4:48; 2:18-22; Matteu 12:38-42; Marku 8:11; 1 Kọrinti 1:22-24

3 Ọkunrin ọlọlá yii fi hàn pe oun ki i ṣe ẹni ti n wá ami, ṣugbọn ẹni ti n fi tinutinu bẹ̀bẹ̀, Johannu 4:49, 50

4 A wo ọmọ naa sàn – ni wakati kan naa ti ọkunrin ọlọlá yii gbagbọ́, Johannu 4:51-54; 11:40; Matteu 17:20; Marku 9:23

**II Oniṣegun Nla ati Alarun Ẹ̀gbà**

1 Awọn ọkunrin mẹrin fi igbagbọ́ wọn hàn nipa ipinnu wọn lati dé ọdọ Jesu, Marku 2:1-4; Galatia 6:9; Gẹnẹsisi 32:26; Matteu 15:21-28; Jakọbu 5:16-18

2 A fi ẹ̀ṣẹ ọkunrin alarun ẹgba yii ji i – eyi ti o fi hàn wa pe oun pẹlu ni igbagbọ́, Marku 2:5; Jakọbu 5:15; Heberu 11:6; Romu 5:1; Filippi 3:9; Jakọbu 1:6, 7

3 Jesu wo alaisan yii sàn fun ẹri nipa agbara Rẹ̀ lati dari ẹ̀ṣẹ jì ni, Marku 2:6-12; 1 Awọn Ọba 18:36-39; Johannu 20:27

**III Oniṣegun Nla ati Adẹtẹ ati Awọn Abirùn Miiran**

1 A wo adẹtẹ yii sàn lojukan naa nipa ifọwọ tọ́ Jesu, Matteu 8:1-4; Johannu 6:37; Lefitiku 14:1-32

2 Balogun ọ̀rún bẹ̀bẹ̀ fun ọmọ-ọdọ rẹ̀ o si fi igbagbọ́, irẹlẹ ati ọ̀wọ̀ hàn, Matteu 8:5-9; Luku 7:1-8

3 Jesu yin balogun ọ̀rún yii, O si bá awọn Ju wi, Matteu 8:10-12; Luku 24:25; Johannu 3:36; Malaki 1:11; Isaiah 59:19

4 A wò ọmọ-ọdọ naa sàn, Matteu 8:13; 9:29

5 Jesu wo iya aya Peteru sàn, Matteu 8:14, 15; Luku 4:38, 39

6 Aṣẹ lati inu Iwe Mimọ́ pe iwosan fun ara wa wà ninu Ẹjẹ Etutu, Matteu 8:16, 17; Isaiah 53:5; Ẹksodu 15:26; 1 Peteru 2:21-24

**IV Jesu, Oluwa Ìgbì ati Afẹfẹ**

1 Nipa lilo awọn apẹẹrẹ ohun ti a mọ̀ daju, Jesu kọ ni nipa jijẹ́ oloootọ sipa ti Ọlọrun, Matteu 8:18-22; 1 Kọrinti 1:27-29; 2 Kọrinti 5:20; Johannu 15:16; Matteu 6:33, 34

2 Igbi omi okun fẹrẹ bo ọkọ̀ ti wọn wọ̀ mọlẹ, Matteu 8:23, 24; Marku 4:37

3 A ba awọn ọmọ-ẹyin ti ẹru n bà wí fun aigbagbọ́ wọn, Matteu 8:25, 26; Marku 4:38, 40

4 Jesu dá igbi naa duro, Matteu 8:26, 27; 14:32; Orin Dafidi 89:9; 107:29; Marku 4:39, 41

## ALAYE

Jesu, Oniṣegun Nla kò ṣe aṣeti rí, bi o ti wù ki arun naa ti a gbe tọ Ọ wa ti le to. Ẹ̀ṣẹ̀, inira ati irora eniyan maa n mu ọkàn Rẹ̀ kaanu, -- ki i ṣe lasan, nitori O ni ipá lati wo gbogbo ẹni ti o ba gbà A gbọ́ sàn patapata. Bawo ni inu wa ti dun to pe eyi ri bẹẹ!

Lẹyin iribọmi Rẹ̀ ninu odo Jọrdani, ati idanwo Rẹ̀ ti o tẹle e, Jesu lọ si Kana ti Galili nibi ti O ti ṣe iṣẹ iyanu Rẹ̀ kin-in-ni, ni sisọ omi di ọti waini. Lẹyin naa O lọ si ilu Kapernaumu, ti o wà lẹba okun Galili. Awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, iya Rẹ̀ ati awọn arakunrin Rẹ̀ wa pẹlu Rẹ̀ ninu irin-ajo yii; ṣugbọn ko duro pẹ ni Kapernaumu nitori akoko ti to fun Ajọ Irekọja ni Jerusalẹmu nigba ti olukuluku ọkunrin ni lati fara hàn niwaju Oluwa. Ọna si Jerusalẹmu jin, niwọn bi a si ti mọ̀, ọna odo Jọrdani ni O gbà lọ.

Jesu ṣe ọpọ iṣẹ-ami nigba ti O wà ni Jerusalẹmu, ọpọlọpọ eniyan si gbà A gbọ́, lara awọn ti o si beere nipa ọna iye ainipẹkun ni Nikodemu. Jesu rin kaakiri Judea, O n waasu Ihinrere Ijọba naa, lẹyin naa O si tun yi pada si iha Galili ati sọdọ awọn ẹni irẹlẹ ti i maa tẹwọgba A nigba gbogbo lakoko iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀. A ti ri i pe irin-ajo yii

mu Un gba aarin ilu Samaria lọ; a si ranti kedere itan isọji ti o bẹ́ silẹ nibẹ, eyi ti ọrọ Rẹ̀ pẹlu obinrin ni lẹba kanga Sikari fà. Ẹkọ yii n sọ nipa awọn ohun ti o ṣẹlẹ ni ọna ajo Rẹ̀ si Galili, lẹyin ti O ti bá obinrin nì pade nidi kanga.

Ohun kin-in-ni ti a kọ silẹ jẹ nipa ọkunrin ọlọlá kan ni Kapernaumu. O ti gbọ́ nipa Jesu, boya nitori omi ti a sọ di ọti waini ni Kana, o si n fẹ ki Jesu wo ọmọ oun sàn. Jesu mu idanwo kan wá lati wo boya ijẹwọ igbagbọ́ rẹ̀ jẹ́ otitọ tabi boya ami lasan ni o n wá, tabi oun gẹgẹ bi ọpọ awọn Ju n fẹ ri iṣẹ ìyanu ti Jesu yoo ṣe lati tẹ́ ọkàn rẹ̀ lọrun. Ṣugbọn Jesu ri igbagbọ́ ati otitọ ọkàn baba ti ọkàn rẹ̀ daamu yii, O si sọ ọrọ ifi-ni-lọkan balẹ diẹ ti o ràn an lọwọ lati gbagbọ́. Ara ọmọ naa dá ni wakati kan naa ti ọkunrin ọlọla yii gbagbọ́!

Jesu kò ri ọmọ naa rí ṣugbọn Ẹmi Ọlọrun mọ ẹni ti i ṣe ati ibi ti o wà, ati nipa ọrọ Kristi, ọmọ naa sàn loju kan naa – ki i ṣe diẹ diẹ gẹgẹ bi aisan iba i ti maa lọ, bi ko ṣe lẹsẹ kan naa ati patapata. Kò ya ni lẹnu pe iwosan rẹ̀ ya ọkunrin ọlọlá naa ati gbogbo ile rẹ̀ lẹnu. A sọ fun ni pe gbogbo wọn gbagbọ́.

A kò le fi alaye lasan tumọ iru iṣẹ-iyanu bayii lọna ti awọn eniyan maa n fẹ fi bu ẹnu ẹ̀tẹ́ lu awamaridi iṣẹ Ọlọrun. Wọn wi pe iwosan jẹ abayọrisi nnkan ti n ṣẹlẹ ninu ọpọlọ eniyan ati pe nigba ti alaisan kan ba gbagbọ́ pe oun le ri iwosan nipa agbara ti o gbagbọ́ pe o wà ninu eniyan kan, eyi maa n ṣe iranwọ fun alaisan naa lati ri iwosan gbà. Ṣugbọn kò si ohun ti o jọ bẹẹ nihin, niwọn bi Jesu kò ti sí nitosi ọmọ alaisan naa. Iṣẹ iyanu ti o ti ọdọ Ẹmi Ọlọrun wá taara ni nipasẹ itoye Ẹjẹ Kristi ti a o ta silẹ lori Agbelebu ni Kalfari.

Jesu kò ṣe iṣẹ-iyanu lati wá okiki, bẹẹ ni kò ṣe ohun abami kan lati fi ṣe iran wò lasan. Gbogbo iṣẹ Rẹ̀ ni o ṣe lọna ti o yatọ si ti ayé. O bọ́ ogo Rẹ̀ silẹ, O si wá bi iranṣẹ, ninu aanu ati ifẹ nikan ṣoṣo, ki i si ṣe fun ère. Nitori bẹẹ nigba ti awọn alaigbagbọ́ Ju n beere fun àmì lọdọ Rẹ̀ -- aṣehàn – O bá wọn wi fun aigbagbọ́ wọn ati fun aigba àmi ti Ọlọrun ti fun wọn tẹlẹ. A ki i fẹ iṣẹ-ami tabi iṣẹ-iyanu kù nibi ti o gbe yẹ lati fi agbara Ọlọrun tabi otitọ ọrọ Rẹ̀ hàn fun ọkàn ti n ṣafẹri nitootọ, ṣugbọn ki i ṣe lati tẹ́ awọn alaigba otitọ gbọ́ lọrun lasan.

Ẹni ti Jesu tun ba pade ni ọkunrin alarun ẹ̀gba kan. Ihinrere ti tan kaakiri pe Jesu wà ni ilu, lai pẹ, ile si ti kun fun ọpọ awọn eniyan ti n fẹ ri I ti wọn si n fẹ gbọ́ ọrọ Rẹ̀. Ọkunrin yii ni ibatan tabi ọrẹ mẹrin ti wọn ni igbagbọ́ nla ninu Jesu. Niwọn bi wọn kò ti le gba aarin ero wá sọdọ Jesu pẹlu alarun ẹ̀gba naa, wọn gbe e gba ori orule ti wọn já kuro, wọn si sọ ọ kalẹ saarin ero ki Jesu ba le ri i.

Jesu ri igbagbọ́ awọn ọkunrin mẹrin wọnyii O si dahun lẹsẹ kan naa. Ṣugbọn ọrọ Rẹ̀ yatọ si eyi ti wọn n reti, Oun kò tilẹ sọrọ nipa aisan ọkunrin yii ṣugbọn O dojukọ ohun ti o pilẹ wahala rẹ̀ -- ọkàn ẹ̀ṣẹ rẹ, Jesu fi ohùn jẹjẹ sọ ọrọ wọnni ti olukuluku ẹlẹṣẹ ti o ba ronupiwada maa n gbọ́ nigba ti o ba fi ọkàn otitọ gbadura. “Ọmọ, a dari ẹ̀ṣẹ rẹ ji ọ” mu ironu wá sinu ọkàn awọn akọwe ti o ti wà nibẹ. “Tali o le dari ẹṣẹ jini bikoṣe ẹnikan, aní Ọlọrun?” ni ibeere ti wọn n bi ara wọn; ṣugbọn Jesu ri ero ọkàn wọn O si mọ aigbagbọ́ ayà wọn.

Awọn ara igba ti inu Bibeli, kò yatọ si awọn ti isisiyii. Bakan naa nisisiyii, awọn alaigbagbọ ati ọlọgbọn ori ni lati ṣe ohun kan ki wọn to le sẹ́ Ọrọ Ọlọrun tabi ṣainaani ẹ̀to Ọlọrun fun igbala eniyan. Wọn ni lati kọkọ fi Kristi pe eniyan kan ṣá ki wọn si mu gbogbo iwa Ọlọrun Rẹ̀ kuro. A ri i pe bẹẹ gẹgẹ ni awọn akọwe wọnyii n ṣe. Loju wọn, Jesu ki i ṣe Ọmọ Ọlọrun; ki i ṣe Oun ni Ẹni ti a rán wá lati Ọrun. Loju wọn O jẹ eniyan kan ṣá -- Olukọni, Oluwa kan – ti ko si yẹ fun ọ̀wọ̀ tabi ọlá ju olukọ tabi olokiki miiran lọ laaarin wọn. Lati gba pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu yoo sọ ọ di dandan fun wọn lati gba A gbọ́ ki wọn si tẹle E, eyi ti wọn kò si fẹ ṣe.

Bi wọn kò ti ni igbagbọ́ lati gba ohun ti wọn kò ri gbọ́ wọn ṣiyemeji pe a ti dari ẹ̀ṣẹ ji ọkunrin naa nigba ti Jesu sọrọ. Niwọn bi iṣẹ-iyanu ti iwosan ti jẹ ohun pataki ju lọ loju wọn ti Jesu le ṣe – nitori wọn lè fi oju aigbagbọ́ wọn ri i – Jesu paṣẹ ki ọkunrin naa dide, ki o gbé akete rẹ̀, ki o si maa lọ si ile rẹ̀. Ọkunrin yii ti ko ti le dá ṣe ohunkohun fun ara rẹ̀ rin jade lọ funra rẹ̀, pẹlu okun nipa ọ̀rọ Jesu. A dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i, a mu un larada a si fun ni ni idaniloju to lati mu ki gbogbo ọkàn otitọ mọ̀ daju pe Jesu ni Kristi naa – Messia ti wọn ti n fi oju sọnà pẹ́ fun.

Gbogbo awọn iṣẹlẹ ti a kọ silẹ ninu ẹ̀kọ́ wa fi ohun kan jọ ara wọn, bi o tilẹ ṣe pe wọn yatọ si ara wọn gẹgẹ bi iroyin eniyan pupọ ṣe le yatọ si ara wọn. Ohun ti wọn fi jọra ni igbagbọ́. Adẹtẹ nì wi pe, “Oluwa, bi iwọ ba fẹ, iwọ le sọ mi di mimọ́,” o si fi igbagbọ́ rẹ̀ ninu agbara Ọmọ Ọlọrun hàn lati wosan ati lati wẹ̀mọ́. Balogun ọ̀rún fi igbagbọ́ rẹ̀ hàn -- igbagbọ́ ti o tobi tobẹẹ gẹẹ ti a kò fi ri iru rẹ̀ ni Israẹli. Iya aya Peteru ni igbẹkẹle ninu ọkàn rẹ pe bi Ọwọ nì ba kan oun lara, aisan ibà oun yoo kuro. A wo adẹtẹ naa sàn! A wo ọmọ-ọdọ balogun ọrun sàn! A mu iya aya Peteru lara dá! Awọn miiran wá pẹlu awọn alailera ati awọn ẹlẹmi-eṣu – O si wo gbogbo wọn sàn!

Imularada jẹ́ ẹkọ kan ti gbogbo ogun ọrun-apaadi dojuja kọ laye ikẹyin yii. Bi Satani ba le mu iyemeji wọ inu ẹni kan lori ọrọ iwosan nipa agbara Ọlọrun, o n fẹ mu ki iru ẹni bẹẹ ṣaigba pe Jesu ni Ọmọ Ọlọrun. Ṣugbọn a ti pese fun iwosan awọn Ọmọ Ọlọrun ninu Ẹjẹ Etutu. Awọn miiran sọ pe Isaiah 53:5 n tọka si iwosan ti ẹmi kò si jẹ mọ́ ti ara rara. Ṣugbọn a ri i ninu ẹkọ wa pe Jesu wo awọn arun ara sàn, O si mu awọn ti ori wọn yí pada bọ̀ sipo, ki asọtẹlẹ yii nipa ijiya Jesu ba le ṣẹ patapata. Ọrọ Ọlọrun ti o ni imisi ni a gboju le nigba ti a ba n wi pe iwosan wà ninu Ẹjẹ Etutu nì. Ẹsẹ kan yii ninu iwe Isaiah ti a tọka si ninu Matteu 8:17 to lati sọ asọpari rẹ̀ pe Ọmọ Ọlọrun ni ẹtọ ati anfaani lati gbẹkẹle Ọlọrun fun iwosan ara rẹ̀. Lati kuna lati gbẹkẹle Ọlọrun fun iwosan ni akoko aisan jẹ ṣiṣe nnkan ti awọn akọwe ṣe: bibu ọlá Jesu kù ati didiwọn agbara Rẹ̀, pipe E ni eniyan kan ṣá. Ṣugbọn awa mọ̀ pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun i ṣe, Ẹlẹda ayé, Olugbala nla araye, ati Oluwosan gbogbo arun wa.

Jesu fi Iwa-Ọlọrun Rẹ̀ hàn ni ọna miiran gbogbo yatọ si mimu awọn olokunrun lara da nikan. O fi hàn pe Oun ni agbara lati dari ẹṣẹ ji ni gẹgẹ bi a ti ri i ni ti alarun ẹgba nì: O tun fi hàn pe Oun ni agbara lori agbara ẹda ati ipa oju ọrun pẹlu. Igbe awọn ọmọ-ẹyin ti ẹ̀ru n ba ni pe: "Oluwa gbà wa: awa gbé" mu ki O dahun pe "Dakẹ jẹ." Rirú igbi naa si duro lẹsẹ kan naa, idákẹrọ́rọ̀ nla si dé.

Bawo ni a ti kuna to lati gbẹkẹle E! Bawo ni aanu Rẹ̀ ti pọ̀ to si wa fun gbogbo aini wa laye! Nipa gbolohun ọrọ kan lati ẹnu Oluwa afẹfẹ ati igbi, igbi wahala ti ó wà ni igbesi-ayé wa le dakẹ. Igbi ipọnju, idanwo, iyiriwo, iyemeji, ati iṣoro gbogbo ni a o pa lẹnu mọ bi a ba ke pe Ẹni ti O le ti ipa ọ̀rọ kan mu idakẹrọ́rọ̀ wa si igbesi-ayé wa.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni ṣe ti a fi n pe Jesu ni Oniṣegun Nla?

2 Bawo ni Jesu ti pe igbagbọ̀ ati ijolootọ ọlọlá ara Kapernaumu ní jà?

3 Ni akoko wo ni a mu ọmọ ọlọlá naa lara dá?

4 Ki ni a ni i ṣe nipa tiwa, ki a ba le ri iwosan?

5 Ewo ni Jesu kà si ohun gúnmọ ju lọ, idariji ẹ̀ṣẹ tabi iwosan ti ara?

6 Bawo ni Jesu ṣe fi hàn pe Oun ni agbara ati ipá lati dariji ni?

7 Ki ni Jesu ṣe nigba ti O wo adẹtẹ nì sàn? Ki ni O wi fun adẹtẹ naa lati ṣe?

8 Ohun amuyẹ wo ni balogun ọrun ti Kapernaumu fi hàn eyi ti o mu un yẹ fun aanu Jesu?

9 Ki ni aṣẹ ti a ni lati sọ pe iwosan wà fun olukuluku ọmọ Ọlọrun?

10 Ka Isaiah 53:5 lori.